# IROHIN IMOLE

*IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA*

No. 1,423 SATURDAY AUGUST 7, 1965 (2D)


3 AUG 1965

## Ijo Onitębomi Fę Şe're Aladun Fun Atilade

EBUTE-METTA:— Ni deede agogo mejo kutukutu owurọ ana ọjọ Eti ti işe ọjọ kẹfa oşu yi ni Irohin de si ile işẹ wa wipe, gbogbo awọn ọmọ Ijọ Onitębomi ni nwọn yio şe ire aladun kekere kan fun Oniwasu, Ęnịọwọ E. A. Atilade, Oniwasu Ijọ 'Gospel Baptist Church" Eko ati Ebute-Metta ninu ile Ọlọrun ni nomba 47. Coate Street, Ebute-Mętta ni dede agogo marun Irọlę oni ọjọ Abamẹta ti işe ọjọ keje oşu yi.

Irohin awọn ọmọ Ijọ na ti a gbọ ni owurọ ana fi ye Iwa wipe, gbogbo awọn ọmọ Ijọ ninu wọn ti ranşẹ si wipe ki gbogbo wọn ma şe alai wa si ibi ohunti awọn enia na fę şe ni irọlę yi.

Ni ọjọ Abamẹta ti işe ọjọ kọkanle lọgbọn oşu ti o kọja lọ yi ni awọn ọmọ Ijọ Gospel Baptist Church Eko şe are ti wọn ti nwọn si pe gbogbo awọn enia lati wa ba awọn worao are aladun na.

Ninu awọn enia jankanjankan ti nwọn wa si ibi are ọjọ na ni Dọkita J. T. Ayọrinde, akọwe agba fun Ijọ Onitębọmi ni Naijiria ati Oke Okun, Dọkita J. A. Adegbitę, Dọkita E. A. Dabunsi, Dọkita A. A. Ajao, Dọkita S. O. Akintọbi, ati

Wo oju ewe kẹfa

# EGBE DEMO TAKU!

## Nwọn Ni Asiko Ibo Ko Ti To

IBADAN:— A gbọ sọgbanu ni irohin ti o ba gbogbo awọn enia ni irọlę ana ọjọ Eti ti işe ọjọ kafę oşu yi nigbati awọn enia na gbo wipe awọn ọmọ ęgbę Dęmọ (N. N. D. P) sọ ni Ibadan wipe awọn ko ti şetan nisisiyi lati tu ile Igbimọ Aşofin Ijọba Ipinlę Iwọ Orun Naijiria ka bęęni asiko ko si ti tun to fun awọn lati tu Ile Igbimọ Aşofin Ijọba Ipinlę na ka nisisiyi bi gbogbo awọn enia kan ti şe nsọfyika Ipinlę na nisisiyi wipe ni ọjọ Aiku ti işe ọjọ kęjọ oşu yi ni Ijọba yio tu ile Igbimọ ne ka.



Alhaji D. S. Adegbero

Ninu ọrọ kan ti o kun oju ewe iwe męta ti akọwe ęgbę na ọgbęni N. A. B. Kotoyę sọ ni Ibadan o ni egbę Dęmọ ko ti şetan rara ti yio tu Ile Igbimọ Asofin na ka rara.

Ọgbęni Kotoyę tilę tun şe afikun ninu ọrọ rę wipe Ijọba Iwọ Orun na ki yio fọgba silę titi di ọjọ kejidinlọgbọn oşu kęsan ọdun yi.

Ọgbęni Kotoyę ni ęgbę Dęmọ ni agbara lati şe eyi nitori o ni eto işelu Iwọ Orun Naijiria fun Ijọba ni aşę lati sun ọjọ na siwaju sii, titi di ọjọ kejidinlọgbọn oşu kęsan ọdun yi.

O wa kilọ fun gbogbo awọn ti nwọn nsọ kakiri lojojumọ pe, ki nwọn ye sọ ohunti wọn ko ri mọ pe Ijọba yio tu ile Igbimọ Iwọ Orun ka ni aipę yi.

Ni ipari ọrọ rę ọgbę ni Kotoyę sọpe, ęni kanna ti o ni agbara lati tu ile Igbimọ Ijọba na ka ni Oloye Samuel Ladoke Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlę Iwọ Orun.

Şugbọn awọn ọmọ ęgbę Itęsiwaju (UPGA ti sọ ni Ibadan ni alę ana wipe ęru lo nba ęgbę Dęmọ ti nwọn ko fi fę tu Ile Igbimọ na ka mọ ni ọjọ kęjọ oşu yi gęgębi ofin ti şe wi wipe, lęhin ti Ijọba kan ba ti lo ọdun marun lori akoso Ijọba Ijọba na gbọdọ tu Ile Igbimo na ka ki awọn enia Ipinlę na si tun dibo lati yan Ijọba miran.

Ni ipari ọrọ awọn ọmọ ęgbę itęsiwaju, awọn ọmọ ęgbę na ni bi ęgbę Dęmọ ba fę ki nwọn tu ile Igbimọ na ka ninu oşu yi, bi nwọn ko ba si fę ki nwọn tun fi ọjọ kun un ju bi o ti şe yę lọ, ohun kan ni awọn gba gbọ ohun na si ni wipe, igba ayowu ti ęgbę Dęmọ ba le tu Ile Igbimo Ijoba na ka ęgbę Afęnifęre ni yio wole ti Ijoba Iwo Orun yio si pada bọ si owo won ni agbara Ọlorun.

Ninu ọrọ awọn ọmọ ęgbę na ni Ibadan ni alę ana ọgbęni Bọla Ige ti işe akọwe ęgbę Afęnifęre ni rogbodiyan kan ti bę silę larin Oloye Akintọla ati Oloye Fani-Kayọde.

Ọgbęni Bola Ige ti lę tun gbe oro rę lęhin pęlu ęri wipe nitori ija yi ni Oloye Akintola ko şe le lo si ibi ipade ti gbogbo awon Alakoso Ijoba şe ni Enugun ni ojo ojo R u ti işe ojo kęrin oşu yi ninu eyiti Alhaji Tafawa Balewa şe alaga won ninu ipade na.

Ọgbęni Bola Ige tun so wipe, oro ija ti o wa larin Oloye Fani-Kayode na po to bęę gęę ti o fi ję wipe, awon Ọba kan ni Ipinlę Iwo Orun ti fę ba won pari ija na, nitori eyi ni Oloye Akintola ko se le lo si ipade ti awon enia yoku ri lo şe

Ni ipari ọrọ rę ọgbęni Bola Ige ni bi oba si ję pe irọ ni ọrọ npa mọ awọn mejeji na ni ki, Oloye Akintọ'a ja on ki o si wa sọ idi rę ti o fi ję pe ki on nikan ni ko lọ si ipade na ninu gbogbo awọn alakoso Ijọba yoku, o ni ki to sọ fun aye gbọ.



Oloye S. L Akintọla

Ninu gbogbo awon Alakoso Ijoba ti nwon lo sinu ipade na ni Dokita Michael Okpara, Oloye Dennis Osadebay, Alhaji Ahmadu Bello, ati Alhaji Tafawa Balewa ti işe Alakoso Apapo Ijoba Naijiria.

Awon enia na ti pari ipade na ni osan ana, gbogbo won yio si pada si Ipinlę won ni owuro yi.

Awon enia ti nwon lo si ipade na ni Iwo Orun ni Ọba C D Akran ti işe Minista Alamojuto èto inawo

# Arẹ Ọna - Kakanfo Ni Ilẹ Yoruba

## Lati Ọwọ S. Ọ. Jaiye

Bi mo ti ka iwe Irohin Imọlẹ ti ọjọ 24 7 65 ni mo ra orun gara ti mo wa ri orukọ mi inu iwe io yi wa pe Omidan Falilatu Arẹag ti Eko mbere itan ilẹ Yoruba nipa oye Arẹ Ọnakakanfo Lẹhin na oni ere yi tun fẹ kin ṣe laaye fun wọn nipa oye Arẹ Ọnakakanfo ti wọn tun fi Oloye Akintola jẹ laipẹ yi?

Owe Yoruba sọ pe ti ọmọde ti ko ba mọ itan ki o lọ bere lọwọ baba tabi iya rẹ baka na lọ so eniti o ba tun dati eniti o mọ itan ju lọ fun idi eyi emi yio gbiyanju lati sọ ibi die ti mo gbọ ati eyi ti mo tun ka fun anfani omidan Arẹago mi oluwadi itan yi.

Bayi ni itan lori oye Ọna kakanfo ti lọ ni ilẹ Yoruba Ki a to lọ siwaju ninu ọrọ yi iṣẹ ki awo awọn Oye mẹta ti o wa ni ilẹ Yoruba ni aiye atijọ ni Ọyọ Mesi

Ẹṣọ ati Kakanfo Ọyọ Mesi ni o kangun si Alafin ta'i Oloye lẹhin ra ni Ẹṣọ tẹle Ọyọ Mẹsi.

Lẹhin eyi Kakanfo ni o wa jẹ ori awọn ipo mejeji nipa ijoko rẹ nitori ipo rẹ ninu Ijọba Alafin. Idi ti o fi ri bẹ nipe nitori Kakanfo jẹ oye Ologun,

Eyi nipe Oye to wa fun abo lori Alafin Ọyọ Mẹsi ati Ẹṣọ ti Ọyọ (Apitan) Awọn ọpitan oye ni Arẹ Ọna Kakanfo eniti o ga julọ ninu awọn Oloye ilẹ Yoruba fun igboya ati awọn eto idabobo ninu ọrẹ ogun jija

Awọn opitan sọ fun ni pe Ọba Ajagbo ni ẹniti o jẹ Ọba kan pataki ni aiye igba ini ti o kọko da Oye Ọna Kakanfo silẹ Ogbogi kini ti o kọ da ni Ọla Oye yi ni Kokoro gangan ti Iaoye ẹniti o jẹ ọkan ninu Onigboya julọ.

A sọ fun ni pe ko si ibiti ogun le to ti Kokoro gangan tabi Kokoro Aro gan gan ninu ogun je pehinda loju ija

Kaka ti yio fi sa loju ija fifọ ni yio fo bi ẹyẹ ti awọn ọta rẹ koni ri mọ Eyi lomu ki Ọba fun ni oye Are Ọna Kakanfo

Gẹgẹbi awọn Ilari ti ṣe na ni eni i a ha fi fi jẹ oye Kakanfo ni lati ṣe Ohun kini ti o ni lati ṣe ni pe ki a fi ri re iro ndiro Lẹhin na a o s n ni i bere mo a u lelugba 201 Bi wọn ti nsia gbere yi i nwọn yio ma fi ogun ti ti pese sile s Ni aiye ig'a na a gba eyi pe fiu ogun yi yio mu ki



Ogbeni S. O. Jaiye

igboya ma wa fun Arẹ Ọna Kakanfo Lati ọjọ ti a ba ti sin igbere wonyi Arẹ Ọna Kakanfo ko ni da irun Ori rẹ si ni kiknn mọ.

Ṣugbọn oju ibi ti a sin igbere wonyi a ko ni fi irun ibẹ me yio wa bi oṣuṣu ṣuru ti irun na yio fi gun to lati di bi irun ori Obinrin.

Itan sọ fun ni pe o fẹ ẹ jẹ wipe gbogbo awọn Arẹ Ọna Kakanfo lo saba ma jẹ alagidi ti o si yigbi lọ-ka lorikankan ati iru awọn iwa akoni ṣugbọn awọn ki ṣe eniti nfa waha a ba ilu rara nitori nwọn wa bi eniti o ni lati dabobo ilu lọwọ ọta

Papa gidi ninu ogun Ọna Kakanfo ki fi ẹh n si ẹ fun en lẹ ni nino chun oh nir nitori ọta ilu ti o fun ni ipo na,

Fun idi eyi a ki yan Kakanfo ninu ilu ti o ba gbe nikẹse ninu awọn igbẹ iko Ọba. Ni ilẹ Yoruba a ye i ta i i ako gb do yan Ọna-Kakanfo me ẹ kan E a ṣa e i an lo i lati wa fun le Y u a Gẹgẹbi aye tabi ipo Ọna-Kakanfo eyi ti o jẹ oye ogun. O ni lati lọ sinu ogun ni ọdun mẹta

Ibikibi ti oba ba yan fun un ni o lati lọ Lẹhin ti a ba ti ran lo si oju ogun kogun pataki ti ọba ni reti ni pe ki o ku sinu ogun tabi ki o bori ogun na titi nkan bi osu mẹta

N bin ni iṣe l le Ọna-Kakanfo le kanri rara. Ohun mẹrin ni a ni I se ami oye Kakanfo Fila oye Ojijiko eyi ti a to iye onde si pẹlu okun tere to san de ibadi Ekeji ni bantẹ penpẹ ti a fi awọ ẹkun han ati awọ ẹlu lati n a fi joko. Ẹkẹta asiso lati ma ko ohun alun ọoi ogun si fun igbera di loju iji Ẹkẹrin ni ọra oye rẹ lati opa aiti ti iṣe pin Oye fun ni jẹ Oye lẹhin afiyesi enia dada Ohun to wa si ọkan mi nipati Akintola nipa Oyekoye t Alafia ba ti fun ẹnikẹni ko s tẹ lati ṣe ahesọ tabi tọ opin ọj i ipa rẹ ya'a siibi ebi rere

Ṣugbọn ohun ti mo mọ Jaji nipa ti Oloye Akintọla lati Ibẹrẹ ati wa pọ ni ilewe nipa Oloye Akintola ko fẹ irẹjẹ tabi itẹmọlẹ lat pada ki i

O si jẹ olugbeja awọn ti ko lagbara ko kọ lati gba ẹṣẹ ni imu yi o tilẹṣepe eje se yọ lara re. Eyi rię i mi lori igba ewe rẹ.

Ṣugbọn nigbati o di ọkun rin tan awọn chun miran

Awọn wọnyi ni Kakanfo ilẹ Yoruba ti igba tokọja titi di oni yi.

| | |
|---|---|
| 1. Kokoro gangan | Lati Iwoye |
| 2 Oyatọpe | Lati Iwoye. |
| 3. Oyabi | Lati Aiase. |
| 4. Adeta. | Lati Jabata |
| 5. Oku | Lati Jabata |
| 6. Afonjaiya l'Iloto | Lati Ilorin |
| 7. Toyeje | Lati Ogbomosho |
| 8. Edun | Lati Gbogun |
| 9 Amepo | Lati Abemo |
| 10 Kurumi | Lati Ijaye |
| 11 Ojo Aburumku | Oghomoshọ 01 (Toyeje |
| 12 Latọsisa lati | Ibadan |
| 13 Akintọla lati | Ogbomọshọ (Loo) |

ọpe ogun patapata.

un fi ye wa si pe ki se gbogbo awọn Kakanfọ ti o lọ sinu ogun Ojọ Aburmaku ti Ogbomosho jẹ ọkan ninu awọn ti ko lọ ogun ni igba ai e re nitori ọtẹ ti nkasẹ ilẹ Alafin ti ri pe alafia t bẹrẹ si jọba lọkan ọmọ enia

Ni koko ọrọ mi gẹgẹbi Falilatu Arẹago ti bere pe kin ṣe alaye lori Oye Arẹ Ọnakakanfọ ti a fi Oloye Akintọla jẹ laipẹ yi Mọ du pẹ fun ibere yi Ṣugbọn Alafia Ọyọ lo le ṣe alaye ki kun nipa re Nitori ti ko ba ndi obinrin ki jẹ kunmolu totọ bi owe ni o Ni ile Yoruba ni igba atijọ Ọba ni nbi oye

Oa n o s ni aṣẹ lọ j ati ti n o ni anfani lati ri awọn o ga ju mi lọ ri kedere ju mi lọ Boya ohun ti wọn ri fi daa ni ọla Oye Arẹ-Ana Kakanfọ fun iṣẹ rere rẹ n ilẹ Yoruba.

Ṣugbọn ohun ka wa ti mo ri to burn ui a wọn Balẹ ilẹ Yoruba miran ti awọn tun nda ni ọ'a oye kekeke kiri

Ni ilẹ Yoruba ko si oye kan ti o tun ni iyi ati ọla ju Arẹ Ọna Kakanfo O da ai ng ati a gbe enia si ipo O'ori ogun ti a tn wa nṣe n alakọbẹrẹ ogun jija

Ẹjẹ ki a ma tẹ siwaju ni jnu ati rere.

Odi g a diẹ na o

---

**E Ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ**

# Iwe si Olotu Irohin Imolẹ

## E K'abọ O, Ẹni-Ọwọ Atilade

Dakun Ol t ,

Jọwọ gba mi ni aye ranpẹ yi ninu iwe Irohin Imolẹ re alakagbadun lati ki Ẹni ọwọ wa Oniwasu E. A. Atilade ku abọ irin ajo rẹ lati ilu Oyinbo nibiti nwọn ti fun bọ lọ kọ ẹkọ kun ẹkọ wọn.

Mo k'Ẹniọwọ Oniwasu Atilade ku irinajo rẹ, Oluwa yio fun ni ẹmi gigun ati alafia ara lati tubọ le ṣe awọn iwe titun miran pẹlu ẹkọ ti nwon tun lo kọ si ni ilu Oyinbo, Oluwa yio ma ṣe amọna wọn ọpolọ nwon ko ni daru.



E. A. ATILADE

Bakanna ni mo si ki gbogbo ẹnyin ọmọ Ijọ Onitẹbomi ati awọn Ijọ Gospel Baptist Church ku amojuba ẹ si ku wahala ojo o Oluwa yio wa pẹlu gbogbo yin o.

Emi ni
Latifu Babalọla
EKO

de lẹgbẹgbẹ lati bere ohun ti o ndun olukuuku wọn lọkan ki a le fi idunnu ṣe gbogbo ohundi a ba nṣe Oluwa jẹki a ko ere oko dele o amin Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi

Emi ni
R. A Bakare
Omu-po Igbomina.

## Ijoba ibilẹ Afijio Eyi Ti Jẹ O

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi laye diẹ ninu iwe yin to njade lolojumọ lati ṣe iwadi ọro yi lẹnu awọn ọmọ ile Igbimọ Ijọba ibilẹ ilu Afijio ati papa julọ Alaga ile Igbimọ Ijọba ibilẹ Afijio pe iwe aṣẹ ti nwọn ngba ki enia to le ṣere eyiti o jẹ pe ṣile mẹwa (10/-) ta bi jubẹ lọ ni wọn ma ngba lọwọ awọn ẹniti o ba fẹ ṣe ẹye ayẹyẹ ti oku igbeyawo tabi ikomọ jade

Mo rope ilu jẹ ohunti o dara larin ilu ko si yẹ ki a tun ma san owo ki a to le lu ilu ni ilu wa atipe ko si ba oju mu lati ri pe iwa ti Ijọba ibilẹ Afijio fẹ ma hu na eleyi yio si dara bi Alaga pẹlu awọn Igbimọ rẹ ba le tun ofin na ṣe Oluwa jẹki Ijọba nyin tu wa lara o mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi ajinde yio ma jẹ

Emi ni
OYETUNDE ADE
EKO

## Musulumi Omupo Ọdi Ọwọ nyin O

Inu mi yio dun bi Olotu ba gba mi ni aye lati kesi awọn Musulumi ilu Omupo lomde ati lagba ati pa pa julọ awọn lẹgbẹlẹgbẹ. Mo ki awọn Alaga Nabiyi ti a ṣe kọja yi ki Oluwa ma ṣe wa ni ada ma le ṣe amin

Mo rope o to ẹgbẹ medo gbọn to wa ni ilu Omu Ipo ṣugbọn kini o fa to jẹ pe ẹgbẹ meji lo wa ninu wọn ati pe bi awọn enia mi sọ nwọn a sọ pe edesiyede to wa nilẹ lo fa tabi pe ko si eto bi edesiyede ṣe tun wa larin nyin bayi to tun mu ẹnyin ọmọ ilu Omu-po ra wa si Nabiyi na?

Ṣugbọn eleyi ba mu loju pe ala i kan ṣe lo mu wọn ṣe bẹ. Mo jeki awọn Musulumi bi awọn enia naohun ti o ṣe awọn ẹgbẹ yoku ko fi wa sibi ipade na

Eleyi yio si dara bi Igbimọ Musulumi ba le pe ipa

## Otito Koro

Inu mi yio dun bi Olotu ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe rẹ to kun fun ọgbọn ati oye ti o njade lojojumọ lede Yoruba lati fun Ọgbẹni kan to pe ara rẹ ni G S ọmọ Esiẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ to ti jade ti pẹ yi ati pe iru ọrọ ti okunrin na fi da esi ọrọ Ọgbẹni Moses Alake ti ilu Esiẹ pada fun ko ba ọgbọn mu ati pe ki iṣe ohun ti o tọ fun ọmọluwabi lati ma gbọ lẹnu oloye eni.

Iru iwa ti okunrin to pe ara rẹ ni G S hu lati ma yọ eke ee bu si awọn enia na ... ojo mu rara Ohunti a mo pe ilu Esiẹ ni idile awọn enia ... emi ko rope nwọn le tabuku si ilu ti awọn ti bi wọn Ṣugbọn otito koro loju awọn ọmọ araiye Eleyi dara bi ọgbẹni G S ba le darukọ ara rẹ ki o ma ṣe fi G S boju.

Emi ni
K S Koṣepa
Esie Igbomina


## EGBOGI JẸDIJẸDI



CYCLOVEN

Aworan egbẹ yi fi han gba ngba ibiti jẹdijẹdi to wa lara rẹ ti nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo Ibẹ ni a npe ni omusu tabi iho idi enia ibiti ẹ ma ngba iṣe igbọnsẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ikan ninu amodi ti o buru, ni pataki fun okunrin ti o si ṣoro pupo lati ṣe iwosan rẹ tan patapata.

Ọpolopo egbogi li owa tia nta kakiri ode isisiyi ti nwọn ma npolowo nwọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boyan ni a le ri mẹwa nin awọn ogun to le ṣe iwosan arun na daradara.

Awọn elomiran lero wipe boya bi wọn gbe lo si ile iwosan lati lo ge eyiti o ba nyo jade ni omusu on nipa bẹ awọn yio bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa koro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyonu rẹ yio si tun bẹrẹ bakanna Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa Ekini ti o bẹrẹ aiko maṣe igbọnsẹ deede tabi lojojumọ, gigun kẹkẹ ologere Basikulu pupọ ẹ'omiran ẹwu ẹran Suga oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugbi jẹdijẹdi orisirisi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o nyo sode ninu omusu tabi ti o ma nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnṣe tabi ti nrin o ninu omusu rẹ ti o ba jẹ bẹ bere egbogi CYCOVEN ti awọn Oyinbo Jamani ṣeṣe wa idi rẹ ki o si dan wo o ri daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata ti a ta nigboro Naijiria bere ni:-

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Lagos
Phone; 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji



## Iwo Ha Nfẹ Ile L'Eko Bi ?

| | | |
|---|---|---|
| Room | | £5 |
| Room and Parlour | | £6 |
| Room and Shop | | £15 |
| Shop and Parlour | | £12 |
| Room at | Idumagbo | £5 |
| | Room | £4 10/- |
| | Room | £4 |
| | Room | £5 |
| | Room & Parlour | £11 |
| | Flat | £18 |
| | Flat | £20 |
| | Shop | £3 |

Ti o ba nfẹ okan ninu awọn ile wọnyi yara tete lo ri Ọgbẹn ODUS:— 187, Bamgbose Street Lagos.

Ni deede agogo mẹrin irọlẹ si agogo mẹfa irole. Ijafara lewu o nafa nla kan ni eyi jẹ fun o pe, ọjọ ile l'Eko



## Kini E Nduro Fun

Bi o ba ni Aṣọ fun fifọ Ati lilọ bi wolen aṣọ oke, Tafẹta Sapẹti ati orişirişi aṣọ ti o ba ni fun fifọ ati lilọ ni Iṣeju kan:-

TETE GBE WA SI ỌDỌ
JYOCE LUNDRY DYING & DRY CLEANING SERVICE
9, Fatiregun St, Brickfield
Apapa Road Ebute Mẹtta

Kia ni ao si fọ ti o ti gba nṣe lẹkan A le wa gba ni ile rẹ ki a ko pada fọ bi aba fọ tan kọ nomba ile rẹ ranṣẹ si wa dan wa wo lẹkanṣoṣo ki o si ri bi iṣẹ wa titi.

Owo pọọku ni a si

## Baba Ku Lojo Ti Nşajoyo Fun omo Rẹ

IT AJANB- IJEBU- ODE; Cbogbo awọn enia to wa şe ajọyọ fun Sunday Ade Okunwoga ti o şeje ti Ilu Oyinbo de ni ọşe ti o kọja yi ni jinnijinni dabo nigbati baba ọmọ şubu lulẹ lojiji lori aga ti o fi jo ko ti o si fi bẹ ku bamuba nu ti gbogbo enia si nşe ha! ha! a ko mọ ri iru eleyi ri. ẹfun abi eedi.

Irohin fi ye wa pe, oloye kan ni Ijẹbu eni ọdun mejidinladọrin ti oruko rẹ nje oloye Odenuga Okuwoga ji ni owuro ọjọ na pẹlu ara lile ti o si wa ọko ayọkẹlẹ re wa si Apapa nibiti awọn ọkọ oju omi ti o ma ako awọn ero ilu oyinbo duro si.

O ki omọ rẹ na nwọn si yọ si arawọn ti nwọn di mọ arawọn nwọn tun fi ẹnu ko ẹnu, nwọn tun sọrọ tọmọ tiya ni gbogbo wọn ba ko sinu motọ ayọkẹlẹ nwọn pada si Ijẹbu Ode.

Nigbati nwọn nlọ si ile, ni nwọn ba fi ẹsẹ kan ya ni Shagamu lati ki arabinrin kan ti oun na şẹşẹ ti Ilu Oyinbo pe de oun na ku orire ti o lọ si ilu Oyinbo ni alafia ti o si de ni alafia.

Onirohin wa ti ọrọ na şe oju rẹ fi ye wa pe nwọn ni ki nwọn fi ounjẹ rampẹ pa ẹnu ki nwọn to tun mu sajo nwọn pọn nwọn si gba bẹẹ logan awọn ohun jijẹ ti npade niwaju wọn.

Bi nwọn ti nşe wahala ti ounjẹ ti yio kari gbogbo awọn alejo na tan ti ounjẹ si ti da ori tabili ti nwọn ẹbara si ounjẹ na tan njẹki nwọn maba ounjẹ lọ ni oloye na ba fi ariwo bọnu pe ye ye iru mi o inu ma wa nrun mi.

Koi ti dakẹ ariwo ti o npa yi ti o fi yi şubu lulẹ lori aga ti o joko le lori ọrọ yi nbi ọrọ miran o ti ku ba mubumu.

Ni awọn enia ti o rogba yika ba sare si lati ran lọwọ ẹ̣rọ ko ba ero mọ gbo gbo wahala nwọn na bọsi asan.

Nwọn si ti gbe oku Oloye na lọ si ile oun ni Ijẹbu Ode fun ayẹwo nkan to şeku pa Oloye na.

Ọlọrun jọwọ jẹki a lo jẹun ọmọ wa o. amin

---

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan22-Feb20) Fi ọwọ Ifa b ọ ẹnu niba mẹta nitoripe ọwọ rẹ yio tẹ owo ifa titi ọjọ li en maşi fa sẹhin ma se suru.

PISCES (Feb21:Mar20) Iwọ ko gbọdọ şe ohun lo ni ẹnikẹni ki nwọn ma ba gbe ire fo ọ da maşe jẹki o j u aanu fi o silẹ.

ARIES (Mar21:April20) Şọra loni nitori ki ovi oju mabe gbe o şubu larin ode gbangba ki o ma ba o li itiju.

TAURUS (April21:May20) Şẹ pẹlẹ pẹlẹ loni p ẹ l a obinrin kan bi o ba başire ti ko gba fun ọ yara fi silẹ ma şe lo agidi pẹlu rẹ.

GEMINI (May21:June21) Şẹ ọmọ ti o ba jẹ ibeji ta bi eya ibeji lore loni ki o si jina si eebu ati iya r e pupọ mbẹ fun ẹ.

CANCER (June22:July22) Maşe fi işẹ rẹ şte ki o ma si şe ko ti obinrin le ara rẹ laitu ki o ma ba il aba mọ.

LEO (July 23 - Aug 22) Obinrin kan nbọ s ba ọ lọ fẹ, nitorina suru ni kio fi şẹgun rẹ ki ọwọ to le tẹ ohunti o fẹ lode re

VIRGO (Aug 23 - Sept 23) Şọra nipa owo inakuna ki o ma ba ke irahun nitori ohunti o nilati şe loru re pọ ju fun ... ki ... tẹju ... ki o m ba da gbese.

LIBRA (Sept 24 - Oct 22) ... da a l i fọjọ osi dara lat wẹ pẹl ... ki o ... bẹrẹ ... ọjọ loni.

SCOPIO (Oct 23 – Nov 22 Şe suru ọrọ ij kan t o ti nbẹ n le nho a y ... şugbọn ọrọ n kon tan ... rẹ

SAGGITTARIUS (Dec 22 Ja 21) I ọ yio ... irohin a du k n l n, s ... i o maşe y n avọn.

CAPRICON (Dec 22 – Jan ... si hunk hun ti şe odi ati şe gboz li odi, b o l w a di odi, bi iwọ ko si ni ẹwẹ a di odi.

## GBANGBA DEKUN! KEDERE BEWO!! BI INA BA WOLE OKUNKUN YIO PARADA IYEN DAJU:





BERE EGBOGI TITUN TI WỌN NPE NI:—

**"DROSELIA"**

Meji rẹ kosi ni igboro Ilu Eko tabi ni Nigeria

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ re ti pẹ tabi ti o nyọ ẹ lẹnu ni akan bi ọdun kan tabi jube lọ, awọn egbogi rọbirọbi ti wọn nta kakiri tabi npolowo ni ori şirişi ko le se iwosan rẹ fara, ma fi owo re şe ofo mọ,

Bere fun egbogi awọn ara ilu Faranşe ti nwọn npe ni "DROSELIA" ojulowo haunhaun atamatase egbogi fun Ikọ egbọ Ikọ ọna ọfun, Ikọ lile. Ikọ ti o mọ mu eni t kẹ ẹbẹ nigb kugba lati inu " Ifun wa (Lungs) tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu. Bi o ba dau Igo kan yi wo Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia Igba aya tabi ọna ọfun re ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio sisan patapata iwọ yio si a jẹun daradara, iwọ yio si sun fọnfọn pẹlu, alafia de si ọ. Bere egbogi yi ati awọn orişirişi. Egbogi Ikọ miran ni Şọbu awọn:-

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street Lagos
Phone 2287 Nigeria (Oja Ita Faji)
ATI NI ŞOBU
IŞẸ OLODUMARE DISPENSARY OKEBỌLA IBADAN
ADEDUN CHEMIST
14, Wakoman Street, Yaba.


---


**Ipoowo Oja Rẹ ko Ti Yege**

*Nitoripe*

O KO TI POLOWO ỌJA RẸ

**SINU IWE IROHIN IMOLE**

T'ODUNKA FUN GBOGBO ENIA

KỌWE IPOLOWO ỌJA RẸ SI ADVERTISEMENT MANAGER

**IROHIN IMỌLẸ**

16 Bamgbọşe Street, Phone 21985 Lagos


---


## Bọ Lọwọ Oşo Ati Ajẹ

Iwe egbogi Ajẹbidan 25/ mejila £2

Iwe Ilana ifa Iyanrin tiṭẹ ati etutu rẹ pẹlu Iwosan 20/-22/ mejila £2 5/-

Iwe Ebo i Aşogba Aru meji 40/-

Ti ad isegun Ajẹ Oşo ati awọn abanijẹ O wa fun itaja pẹlu alakala Pangolo 10/ Pakẹti 2/- Ki işe ti ẹni fifọn bi ra ninu awọn ọjẹ yi aabo ti o nipọn ni ile aiye ni yio wa lori rẹ ati awọn ẹbi rẹ.

Fi owo ranşe si
J O SHOYINKA
11, Aliba Street
Odunbọrẹ Mushin.

